# ORI OKE INA ATI IṢẸ IYANU

*Olu Ile Iṣẹ Iranṣẹ, Ipinlẹ Eko, Nigeria.*

# ETO IPADE AGBARA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ AṢAYAN NINI ASOPỌ PẸLU ẸJẸ IREKỌJA TI JESU

Bibeli Kika – Orin Dafidi 91, Ẹksodu 12

Ijẹwọ - Ifihan 12:11; Ẹksodu 12:14

## A NI LATI MAA GBA AWỌN ADURA YI TITI DI IGBA TI A O FI BẸRẸ ETO ADURA ATI AWẸ TI AADỌRUN ỌJỌ WA

1. Krist'Olugbala ku lori 'gi
O ku f'ẹlẹṣẹ, san gbese rẹ
F'ẹj'Ọdagutan wọn ọkan rẹ
N o re ọ kọja re ọ kọja.

**Egbe:** 'Gba mo ba r'ẹjẹ na
'Gba mo ba r'ẹjẹ na
'Gba mo ba r'ẹjẹ na
N o re ọ kọja, re ọ kọja

2. Jesu ngbẹlẹṣẹ to buru ju
Yo mu gbogbo ileri rẹ ṣẹ
Wẹ ninu isun to nwẹṣẹ mọ
N o re ọ kọja, re ọ kọja.

3. 'Dajọ mbọ, oju gbogbo yo pe
A o gba ere ti o tọ si wa
Ri sinu ẹjẹ ti nwẹṣẹ mọ
N o re ọ kọja, re ọ kọja.

4. Anu titobi ifẹ yanu
'Ṣeun ifẹ, o tọ at'ododo
Wa alafia n'nu ẹjẹ na
N o re ọ kọja, rẹ ọ kọja.

***Orin Iyin ati Ijọsin***

1. Ọlọrun, jẹ ki ina Isọji ba le Ijọ Ori Oke Ina ati Iṣẹ Iyanu, ni orukọ Jesu.
2. Ọlorun dide, ki O si fun wa ni awọn adari ti o ni ibẹru Rẹ, ni orukọ Jesu.
3. Baba, a jẹwọ a si ronupiwada kuro ninu ẹṣẹ ti o ṣilẹkun silẹ fun ajakalẹ arun yi, ni orukọ Jesu.
4. Oluwa, jẹ ki aanu Rẹ fọhun ki O si ṣaanu fun wa gẹgẹ bii Orilẹ-ede, ni orukọ Jesu.
5. A gbeede, a si le dragoni alade lati Ila-oorun jade kuro ni ilẹ wa, ni orukọ Jesu.
6. Agbara Ọlọrun ọga ogo, Ṣiji bo awọn ti nwa iwosan ati abo, ni orukọ Jesu.
7. Ajẹsara atokewa, nipa ẹjẹ Jesu, ṣijibo awọn oniṣẹ ilera wa, ni orukọ Jesu.
8. Oluwa, fun awọn adari wa ni ọgbọn at'okewa lati ṣẹgun lasigbo yi, ni orukọ Jesu.
9. A paṣẹ ki afẹfẹ pọ gbogbo irugbin ati ami iku ti o ti gbemi, ni orukọ Jesu.
10. Ẹṣeun Baba fun awọn anfani ati ipese ti ẹjẹ Jesu.
11. Odi ẹjẹ Jesu yi emi ati idile mi kakiri, ipa buburu iyowu ti o ba sunmọ wa yoo jona, ni orukọ Jesu.
12. Ẹjẹ irekọja ti Jesu , ṣiji bo orilẹ-ede wa, ni orukọ Jesu.
13. Ẹjẹ irekọja ti Jesu , ṣiji bo ilẹ wa, ni orukọ Jesu.
14. Ẹjẹ irekọja ti Jesu, ṣiji bo emi ati idile mi, ni orukọ Jesu.
15. Nipa agbara ti mbẹ ninu ẹjẹ Jesu, a dẹkun itankalẹ ajakalẹ arun yi, ni orukọ Jesu.
16. Mo fa ila ti ẹjẹ Jesu yi ara mi ka lodi si gbogbo ọfa ailera, ni orukọ Jesu.
17. Mo ṣẹgun gbogbo ẹmi ailera nipa ẹjẹ Ọdọ Agutan, ni orukọ Jesu.
18. Mo lo ẹjẹ esu sori gbogbo aisan ti o f'arasin ninu aye mi, ni orukọ Jesu.
19. Ki ẹjẹ Jesu sọrọ idarudapọ sinu agọ awọn ọta mi, ni orukọ Jesu.
20. Ki ẹjẹ Jesu sọrọ alafia sinu gbogbo ẹya ara mi, ni orukọ Jesu.
21. Ki ẹjẹ Jesu sọrọ ijakulẹ si gbogbo iṣẹ buburu ninu aye mi, ni orukọ Jesu.
22. Ẹjẹ Jesu, sọrọ awọn ohun ti o dara sinu aye mi, ni orukọ Jesu.
23. Mo gbede, mo si le jade, gbogbo ẹmi ibẹru, ni orukọ Jesu.
24. Ki agbara igbala ati iwosan ṣiji bo orilẹ-ede yi, ni orukọ Jesu.

ILE IṢE IRANSE ORI OKE INA ATI IṢE IYANU